# KINIUN OLOWOGBOWO LQ SI QRUN ALAKEJI

## Ikede

Ase ikede yi [illegible] gbogbo onibara Okowo wa ati asoju wa wipe, eni kan ti owo ba taku si owo re ki o tete fi ranse nitori gbogbo oruko eni to ti a fi owo re sile lo ti gbe owo lori.

Enikeni ti ko ba fi tire ranse ao da iwe re duro ao si se agbara lati gba owo wa ni owo re. Olotu.


ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO


### ISIMI WA FUN GBOGBO ILE YORUBA

IBADAN — Lana ni ibere Eko Ogbeni sakiri ni gbogbo ile Yoruba [illegible] isimi wa fun gbogbo awon omo Olowo [illegible] lati ojo 14th titi 15th ojo Jan 1955 [illegible] gbogbo awon [illegible] ni yio le fi ese fun Oluwa ninu Mosalasi ati ninu Soosi fun ojo na to soju emi


VOL. VII No. 398 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA JANUARY 15 1955, IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI




Awon ti a nwo ninu aworan yi ni awon Hausa lori ijoko won ninu igbimo asofin gbogbo gbo (House of Representatives)

## Kiniun Olowogbowo Lo Si Qrun Alakeji

EKO—Irohin ko to afojuba, nigba ti a gbo iku Ogbeni Alagba Hon. Samuel Herbert Pearse, Fellow of Royal Geographical Society, awon eniti ko le ran ni ki a gbe won, o dagba to ara adorun odun nigbati o fi aiye sile.

Eyi ni itan kukuru nipa igbesi aiye ologbe yi Samuel Pearse je okan ninu awon omo ologbe eniowo Samuel Pearse ti ij[illegible] sosi Ebute-Ero on ni a npe ni Awobo, ninu ilewe C. M. S. Grammar School li o gbe ko iwe lati odun 1879 titi di 1883 ki o to jade.



OLOGBE Hon. S. HERBERT PEARSE

O bere ise akowe labe Ogbeni Ologbe Z. A. Williams ara ilu Eko On pelu Ogbeni Ologbe Thompson lo jijo da owo po, nwon si nje oruko Pearse and Thompson.

A yan si igbimo Asofin ti ilu Eko ni odun 1915. O si da owo repete ninu War Relief Funds. o si je okan pataki ninu ijo Anglican Communion ti Eko On kan a ni Olotu ilese itewe ti a npe ni Awobo Press.

Ijoba tun yan a gegebi asoju fun gbogbo ile Egba ninu igbimo asofin Eko ni odun 1923 O se akowe olutoju ile egbe Glover Memorial Hall O si tun je okan ninu awon iko ti a ran lo silu Oba nipa oro ile o si je okan ninu awon ti o soro lohun, niwaju Alagba Sir Kenelm Digby li odun 1913

Ijoba tun yan a latise Baba egbe fun igbimo Lagos Chamber of Commerce and Industries. Awon eyinbo nwonyi je aladugbe ati ore nigba aiye re- Ogbeni R. M. Williams, Richard Barrow, F. H. Smart, D. D. Jones ati J. J. Johnstone, gbogbo wonni General Manager U. A. C. Ati Ogbeni Hunter, Manager Oyinbo Onisowo John Holt

Samuel Herbert Pearse ni a npe ni Onile Elerin ni Oke-Olowogbowo.

## Ao Dibo Miran Losu To Mbo

**Eko** Aye meji lo si sile ninu igbimo Lagos Town Council ao si dibo yan elomiran si awon aye na lojo 15th Feb 1955 awon enia meji na ni Ogbeni Rotimi Williams eniti o fi igbimo yi sile bo sinu aye nla kan ni Ibadan.

(Minister of Justic ati Minister of Local Govt.) Sugbon igbimo li o yo Ogbeni Ndaka Eze omo egbe N.C.N.C. nitoripe ko se deede ninu igbimo. Ibiti ao dibo si ni Ward B Div. 3 ati Ward C. Div. 5.

## Olola Awolowo



Eniti a nwo yi ni Ogbeni Obafemi Awolowo on ni Olotu egbe Afenifere (Action Group)

## EFUN NI EYI TABI EDI

**Eko** Okunrin gbajumo kan ti Olopa rimu nitoripe o lo ji bata titun meji nigbati Olopa mu de iwaju adajo nwon bere nipe boya o ni ise ti kosise

O dahun pe on nsise loju mejeji sugbon araiye ti gbe agbara fun on tobe ti on ko mo ibiti on nna owo na si

Nwon tun bere pe kilo fa ki o to lo ji bata? O dahun pe on buno obinrin ti o fe ma wo bata Stand bye, beni owo ko si lowo on, omo on ko si gbodo doti li o de.

Nigbana ni adajo so fun wipe on yio ran lo si ogba ewon ibiti nwon o gbe wo gbogbo arun re san Nitorina ki o yara lo si ewon osu mesan pelu ise ase gan.


# PUBLIC NOTICE

Applications are invited for the post of Clerk Assistant, House of Representatives, Lagos. Particulars in Government Notice No. 28 in the Federation of Nigeria Official Gazette of 6th January. Application to Secretary, Federal Public Service Commission, Private Bag No. 2586, Lagos. Closing date 12th February.

# ELETI QFE

A-NSU-WON KO SI WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS — 82, Kosoko Street, Lagos — P. O. Box 860

CABLES & TELEGRAMS "ETI-QFE LAGOS" — Phone 23379

VOL. XII NO. 98. LAGOS SATURDAY JAN. 15 1955.


## Bawo Ni Ijoba N. C. N. C. Yio Ti Ri

Ijoba ile Nigeria ti bo si owo awon egbe N.C.N.C. lati ojo 12th osu Jan 1955. A fe lati se alaye oro yi fun enyin okawe wa ti gbogbo oro na ko ye to. Bi oro na ti lo ni wipe, ninu igbimo awon Asofin ti a npe ni (Council of Ministers) omo egbe ti N. C. N. C. li o poju.

Ninu awon enia dudu mewa ti o ni lati wa ninu igbimo yi, mefa ninu won je ti egbe N. C. N. C meta je ti Hausa okan soso si je ti Kameru. L a i s i tabi-tabi, enikeni ti mo wipe owo N.C.N.C. ni kuku ida ijoba ile Nigeria bo si, Sugbon bawo ni awon egbe yi yio ti lo kuku ida na si. Bi o ba je wipe egbe rere ni won, gbogbo wa ni yio laju sile ri, ewe bi nwon ba si je egbe buruku, oju gbogbo wa ni yio ja bakanna.

Gbogbo wa l i o ti ri ise owo olukuluku egbe oselu ti o mbe ni ile Nigeria ninu awon ilu ti nwon ujoba le lori. Awon egbe Afenifere (A. G.) lo ni ijoba ile Yoruba nikawo, ti awon egbe N. C. N. C. ni apa Ila Orun, ti awon egbe N. P. C. ni gbogbo ile Hausa loke Oya.

Bi a ba sakiyesi dara-dara, ti a si wo lati ehin wa gegebi awon egbe oselu meteta nwonyi ti nsise si, awa paapa yio mo laife wipe, enikan so fun ni iru egbe ti o ti mu ilosiwaju ati idagba-soke wa si ilu tire.

Sugbon nisisiyi ti egbe ijoba Nigeria le egbe N.C. N.C. lowo, e jeki a deju sile, lati wo bi igbehin oro na yio ti ri, ni gbigbe ijoba ile yi gunle si ebute rere lahin osu mejidilogun ti nwon o fi gbe ate ijoba na ru.

Owe kan so wipe, apa agbelcka ti ehin loju, eyi ni idi ti a fi bere wipe bawo ni ijoba N.C.N.C. yio ti ri o?

## Egypt Gba Ilu Suez Pada

**Kairo** Ilu Suez ti o je kan ti o mbe lori Ebute Odo Nile ati Okun Mediterania, ti o si mbe ni agbegbe ile Egypt, nibiti awon Gesi ti fidiri si lati ya ara won kuro lara awon ara ile Egypt ilu yi ni pataki ohun ti o da akitiyan sile larin Gesi ati Egypt.

A gbo wipe awon Gesi ko fe lati fi ilu Suez sile awon ni nle se,ni ti ara won. Sugbon awon ara Egypt fi agbara jijakadi na, nwon si gba ilu na lojo 1st osu Jan, 1955.


## Imoran Fun Eyin Abiyamo

Enyin abiyamo gba ra **'Omorela'** *O dara popo fun awon omode*

A mo je ki omode ri orun sun daradara, o dara fun etutu, iko ati onyirun ataro inuno ti o mu ara omode ja si asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun awon won ti won si so wipe o dara popo fun awon omode.

**Omorela Baby Mixture**

SILE MEJI ABO (2/6d) FUN IGO KAN

wa lodo

**Commercial Medicine Stores**

QUALIFIED CHEMIST

15 Victoria Street, LAGOS.


## Mo Yo Folomo



Eniti a nwo yi ni Qgbeni Nnamdi Azikiwe on ni olori N.C.N.C.

**Idanre** Ogbeni Gbadamosi Adegun ara Ile Ila Orangun ati Rabiatu Moyo ba da iyawo re ni Oloruń li omo Tirun jojolo kan ra lo ni osu Dec 1954

Baba tunfelu ni bere si dawo omo na pelu owo ode ni nina, nitoriti omo na je angbo re Alafa ara Ilorin meji lo wa se Sina oruko omo na Alafa Yesufu Amoda lo ke wusuba Alafa Adisa. Ati ewoyo lo se adura awon si fun omo na ni oruko yi, Sakariyau Lati o run genawe repete ni Abade Karimu Adebisi Akande, ti ogo baba Tufelu yi.

Die ninu awon enia pataki ti o wa ibe ni Qgbeni Raji Adeleke, Gbadamosi Ekeria, Oke Tailor, Kolawole, S. Adekoiye, Rafatu Ebe Rafatu Abike, I Akinyemi; F. Akinbo L. Gbose, S. Adeniyi.

## Qba Obinrin Ilu Oyinbo



Eniti a nwo yi ni Alaiyeluwa Qba obinrin ilu oyinbo Gesi on ni usisi o ranse yi si igbimo titun ti o sese bere bayi wipe:-

Mo ti se akiyesi nyin nigba pupo, inu mi si dun jojo lati so wipe iru ilosiwaju ti e ni nipa eto ofin titun ile nyin jo mi loju gidigidi. Eru wiwuwo ni ofin titun yi gbe ka ori enyin igbimo, ki se fun ile ilu nyin nikan, sugbon ki e le ni ajumose ati ifowo so o o po ninu isofin agbegbe ile nyin ati ilu Kameru. Mo ni igbekele wipe olukuluku awon igbimo yio gbe eru ire pelu otito ati ododo

Ki e to daju enyin ona mi wipe, lati ojo oni ti e si igbimo yi lo, emi yio bere si so bisi ati ihuwasi enyin, adura mi si ni wipe, ki Olorun so amona nyin ninu gbogbo oso ti e ba nse, ki ohun gbogbo ti e ba se le ogo ati ire ilosiwaju ilu nyin.

# Irohin Lati Ilu Okere

## Bi Jamba To Sele Ni Eko Ti Po To

**Eko** Oga awon Ọlọpa fi han wipe larin oṣu April si oṣu Dec. 1954, aṣapọ gbogbo jamba ti o ṣẹlẹ nigbero ilu Eko je Ẹgbala-marun-di-logorun (2,095)

Ninu oṣu Keresi mesi ti o koja lọ yi nikan iye jamba t' o ṣele ni ilu Eko ninu oṣu na je igba din-merin-dilogun.

Oṣua pataki ti o si fa jamba nwonyi wa ni awon oniwakuwa bicycle ti o gun keke laisi akiyesi tabi isibikita fun moto ti o mbọ nwon ko si tele ofin oju ọna moto yala moto mbọ tabi ko wa nwon o wule sare la arin oju ọna kọja O yẹ ki awon Onikeke mọ wipe emi ti nwon loju ti Driver moto die le je nigbati moto ba ko lu won ki owo si akiyesi wipe gegebi moto ti pọ niwon ogun ọdun sehin ti asiko yi pọ ju be lọ nigba egberun.

Ẹnyin Obi e fa awon ọmọ nyin keke li eti ti nwon koli mọ keke ni gigun ti awon nta felefele ni waju moto Ẹsọ di ọwọ nyin o, ti pe.

## Ọgba Ewon Dan Ju Igboro Ilu Lo

**Enugun** Okunrin kan ti a npe ni William Momọ ni ni Ọlọpa ramu fun esun wipe o nringba-raye kakiri ilu laiṣe iṣẹ kan. adajo si ṣe ikilọ fun wipe ki o lọ ṣo ara rẹ, en ko gbọdọ tun ri ninu kote mọ.

Okunrin na fi igboju sọ fun Adajọ wipe Maṣe gbe inu ile ni ibikan dandan ni oluwa rẹ yio sa gbe. Nitoripe Iwo adajọ bi o ba fẹ, iwo le ju mi sinu ewon, nitoripe ọgba ewon san ju igboro ilu lọ, En e ko le ri iṣẹ ṣe ni kiakia bi enia yio ba si rẹẹ ṣe o ni lati gba aseko.

Ofin ko si gba fun ẹniti o ti lọ si ẹwọn bi emi lati ma ringba-araye kakiri ilu, beni a ko si le joko ninu ile ki iṣẹ wa ba ni maṣu, m a t u ibikan dandan ni so ṣu si.

Ọkunrin na tọlẹ tele i: onibara awon Ọlọpa, o si ti awo ẹwọn ojọ

## Awon Japan Ko Fe Oja Ile Wa

**Eko** Nipa ipade kan ti aṣoju ilu Japan ati Minister ẹgbe Commerce and Industries ṣe laipe yi.

Aṣoju ilu Japan dahun si ibere kan bayi wipe awon ara ilu on ko wa Koko tabi Ekuro, tabi Epo tabi Roba lati ra, ohun ti nwon wa ṣe ni wipe, lati mọ ira awon oja ti a nfe aile wa ki nwon si ma ko won wa fun wa. Eyi ni ko jeki ijọba gba won laye lati ra oja kokan lọ si Japan.

## Iku Lo Lori Enia Nwonyi

**Eko** Awon enia meji nwonyi Williams Akpan Udo ati Arit Asuquo awon eniti ijoba fi sun wipe awon li o pa Unwa Akpan ati Iquo Essien ninu Kote ile Kelsba niwaju adajọ Agba n'lu Aba ati Uyo, ti a si dajọ fun wọn wipe ki a lọ yẹg fun won.

Nigbati Gomina Agba ati awon ile imọ rẹ joko ṣe gbimọ lori emi awon enia mejeji wọnyi, nwon ṣe ipinu wipe kaka ki a yegi fun awọn enia nwonyi ki nwọn ma gbe ọgba ewon titi opin emi wọn.

## Ọkunrin Kan Gbe Iwe Mi

**Eko** Odomọkunrin kan ti o nṣiṣẹ ni ilesẹ oyinbo Aṣoju ti Eko ni a gbo wipe o ṣe iwe moderu kan lati fi jẹri wipe lotitọ li o gba owo ọrọ si di ti ọlọpa.

Adajọ bere lowo ọkunrin ọdaran yi bi o ba jẹbi ọran na? O dahun wipe, Ndao on ko jẹbi ati wipe on ko ṣe iwe fun ẹnikan wipe on gba owo.

Nigbana ni Adajọ ni ki nwọn fi risiti na han a wipe, tani ṣe iwe yi? Ọdaran na gba a o ri ri wipe nitotọ ni on ṣe iwe

Lasekanna o ka a rogodo o si ju si ẹnu ki awon ọlọpa to de ibẹ okunrin na tẹ gbemi. Bayi ni ọjọ na ba dun nigbati nwon ko ri nkan i ba rojọ.


## REAL OPPORTUNITY FOR TRADERS

Iron-Sheets, Cement, Stockfish All kinds of Beer, Gin, Salt 40 lbs, Large Sweet mineral Waters, Flour, 100 lbs, Caustic Soda, Stout Beer.

Buy the Medicines:

Jedijedi and Jaarun Bitter Tonics Pile Tablets, Cough Mixtures, Tonics, Quinine Mixture, Metatone Eye drops, Earache drops, Toothache drops, Worm Expeller

### ASTHMA CIGARETTE

This is good for asthma Bronchitis, Weeping Cough & Shortness of Breath etc, etc.

While assuring you of all our best attention at all times,

Buy the cheapest and Best articles and Medicine from :-

**J. A. AJAO BROTHERS**

10, Egerton Road, P. O. Box 38 Lagos, Nigeria.







## MEDICAL DEPARTMENT

Vacancies for Government Student Nurses in Lagos Preliminary Nurses Training School, Lagos.

Applications are invited from girls of Modern II Standard and upwards for entrance to the Government Nurses Preliminary Training School, Lagos commencing in April, 1955.

2. All applications with details of educational testimonials should be made in writing not later than 31st January, 1955, and marked "CONFIDENTIAL" and addressed to the:-

SENIOR MEDICAL OFFICER,
BROAD STREET,
LAGOS.

3. The application should be accompanied with the following documents:

(a) Copy of School Leaving Certificate Modern II or Government Secondary IV.
(b) Copy of Birth Certificate.
(c) Copies of three recent testimonials (One from Headmaster or most recent employer)

4. Unsuitable applicants will not be notified; suitable candidates will be asked to report for interview bringing Original Certificates for perusal.

5. The course last six months with subsistence allowance of £7 per month and successful students thereafter proceed to the General Hospital, Lagos or Massey Street Dispensary as Nurses and/or Midwives-in-training.

SENIOR MEDICAL OFFICER, LAGOS.

## Oba Ikenne Wuye

**Ikenne** Nitosi awon ara ilu Ikenne nigbati Alayeluwa S. O. Awosemi oba ilu Ikenne nse iwuye re ni ana.

Gbogbo awon ijoye ilu, awon egbe Awo, Ereja ati awon obinrin oja gbogbo, ni o wa nibi Odi to soja, awon si kori si inu oja nibi ti ao gbe se iwuye na.

Okan ti awon nkan ti gbe igbe nibiti Olofin Awolowo ni gbogbo enia ti duro si ile igbe Awo! Awo! Awo! awon omode ti o de ile akoko ni odiji ti awon ti gbe inu ile ara a. Nibi eto iwuye yi ni ati se eto lati fi Awolowo joye Losi ilu Ikenne ati iyawo re si je oye Mojibade ilu Ikenne.

Die ninu awon gbajumo ti wa nibe ni, Ogbeni F. R. A. Williams B. A. F. Kayode, M. A. Ogun, S. L. Akintola, S. O. Sosibare, Ola Adigun, A. Rewane, J. Adelusi, A. Rosiji ati awon Minister ile Yoruba.

## Ara Epe Kan Wa Be Wa Wo

**Epe** Ogbeni Musibawu Gafaru, omo a epe ni Holy Boy ilu Epe ti o si ti nse asoju iwe Irohin Eleti Ofe da kan wa be ile se iwe Irohin yi wo, o si ti pada lo si ilu re, Oko arelo o Holy Boy.


## Ose Palmolive Le Jeki Ara Re Ro, Ki o Se Fulofulo Larin Ojo Merinla



**Ewa jade lara mi nitoripe motele ilana ti Dokita se**




Epo Ile Afrika ni a fi se


## Imale Nsin Olorun Igbagbo Nyin i

Olotu,

Jowo gba mi laye lati dahun si ibeere meteta ti ogbeni Taiwo Olorunsola bere. Ekini ni wipe nipa Olowo ati gbajumo. Tanije Idahun mi ni wipe gbajumo ju Olowo lo nitori ohun pupo ni a le figbajumo se ti olowo ko le se e.

Ekeji. Ninu Iya eni, ati ore eni tani ju? lojo temi ore eni ju iya lo ore tooto ni mo wi ko nse ore dabiayanke.

Eketa ni wipe a nsin Olorun ni tabi a nyin. Idahun temi niyi. Nse ni awon Onigbagbo nyin Idahun niyin Olorun logo nitoripe awon ko ti ri ojo Jesu ti awon tele ko fi ona ibi han won nsin Olorun nigba marun lojumo, sugbon ekan soso lojo meje ni Igbagbo ma nfi orin ki olorun ti oro na ti je niyen.

Emi ni,
L. Aiwini,
Ara Ibadan.

## Isipaiya Si Ajala Ara Dandume

Olotu,

Idi re ti mo se ajala ara ilu Dandume leke Oya ni iyanju ni wipe gbogbo oro ti O ba ti enu awon Woli wa tabi eyiti o ba ti enu Olorun wa, ko ni tase ara won. Jesu paapa se wipe titi orun on aiye yio fi koja ora on ko ni tase lailai. Esin imale dara ju.

E wo iwe Johanu 5. 31. Ore ti o be nibin yato si Johanu 8. 14 beni Jesu kanna ni a gbo pe o soro ti o tako ara wonyi.

Ninu iwe Woli Isaiah 45,23. Olorun ti enu Woli Isaiah so wipe gbogbo orunkun ni yio wole fun on, gbogbo ahan ni yio si bura, sugbon Iwe ihinrere Matt 5, 34. je Olorun niyan niwipe lotito ni mo wifun nyin, ki ebikeni mase bura rara.

Bi mo ba wipe ki nma fa iru oro wonyi jade ninu Bibeli oro pa nibe. Sugbon ngo tun fun e ni okan ni awon oba keji 8. 26. so wipe Ahasia wa ni omo odun mejilelogun nigbati o joba. sugbon iwe Kronika keji 22. 2 so wipe omo odun mejilelogoji ni Ahassia nigbati o bere si joba Eyi fihan wipe ko si afose mo mo ninu Bibeli

Emi ni
Lemomu Ajakuta.

## Tali O Ju Ninu Awon Meteta Yi

Olotu,

Jowo gba mi laye lati se abere yi ledo awon onkawe re ki awon fi ye wa, tabi o ju ninu awon enia ninia meta owonyi.

Olola gegebi Minister.
Olowo, gegebi Millioneer.
Ole-Ogun gegebi Dokita.
Ki awon ti le idi re bawo ni awon se ju ara won lo.

Emi ni
B. Ade Ajagbe
Ara Isagbiji

# Aradan Nervigora

Ogun eje pataki fun imarale agbo ati fategbe pipe fun awon alaya papo. O dara fun marun, eje dudu, sokun oju, gbigbon owo, aiesun, ailokun ara, ati irole arun bawonni. O je ajidewe fun awon ti agbara won nbike. On na gan ni okunrin yi le ti o f'di "Afise kun bi ojo" 5/-6d pere ni pelu owo oko 1/-6d.




## The Egba Trading Aradan Stores

144, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box, 2, Ebute Metta. Phone 44153, a tun wa ni New Motor Park (Ogunpa Ibadan.


# KINGS COLLEGE LAGOS

## Entrance And Scholarship Examination 1955

The Entrance and Scholarship Examination for admission to King's College in January, 1956 will be held on April 2nd, 1955.

2. "Candidates wishing to enter for this examination will receive application forms, particulars of Scholarships and conditions of entry by carrying out the following instructions :-

(1) Put your name and full postal address on an empty, open foolscap envelope ( a foolscap envelope measures 9 ins. by 4 ins.)

(2) Stick a 2d. stamp in the top right-hand corner of this envelope.

(3) Put the stamped addressed envelope inside another, addressed to :

The Registrar of Examinations (K.C.)
Federal Office of Education,
LAGOS

and post it to reach the Registrar of Examinations not later than February 12 1955.

Application forms will not be sent to any candidate who does not carry out the above instructions exactly and no correspondence will be entered into about these forms. The Registrar will not receive applications in person and will not interview any intending candidates."

3. The application form will give full instructions on the method of applying for entry to the Examination.

4. Requests for forms will not be considered after 12th February, 1955, and completed application forms must reach the Registrar of Examinations not later than 26th February, 1955.

## Awon Ara Ilu Gbogan Da Egbe Titun Sile

**Gbogan** Bi o ba egbo, gbo, gbo, bi iwo ko ba te-te ba won gbo, ebinkule oluwa re ni awon o gbe ju si. Olukuluku ilu l'o nsise fun igbega ilu tie, ninu eyi ni awon ara Gbogan gb. ese kan siwaju.

Nwon se idasile egbe kan ti a npe ni egbe ibile Gbogan (Gbogan Progressive Union.) Ese awon gbajumo ati bereokini ilu na lo pesinu egbe na. Ohun ti nwon da egbe na sile fun ni lati mu wa ire ati ilosiwaju ilu Gbogan.

Die ninu awon gbajumo ti o mbe ninu egbe na ni C. A. Oketayo, T. O Osi, L. Dare, A. A. Agbaje, G. O. Popoola, R. Odeleye, J. O. Orisadiya, Y. Asabi S. K. Ayodeji A. Adeyemo, L. Babatunde, E. Fatoye Adeobigbe, O Taiwo, J. Adeniyi V. Odeleye.

## Rogbodiyan Ilu Oyinbo Kan Won Ni Ibadan

**Ibadan** A gbo irohin wipe ijoba ile yoruba ranse orisirisi awon iwe ti awon omo ile eko yio ma lo nigbati nwon ba bere eko olofe ti ijoba se fun won.

Awon iwe na ko si tete de, Ohun ti a gbo wipe o fa pipe re ni wipe awon osise binu da ise sile ni ilu Oba lohun, gbogbo awon iwe kika kiko, isiro, gbogbo re li o ti tan.

Sugbon nisisiyi ti a gbo wipe awon osise na ti bere ise a li ero wipe ki osu to pari awon iwe eko nwonyi yio ti de ni yanturu.

Nigbana olukuluku awon obi yio ri iwe ra fun awon omo won.


# REDIFFUSION

LISTENERS

**E**NJOY
**D**AILY
**I**NTEREST AND ENTERTAINMENT
**F**ROM 6 A.M TILL 11 P.M
**U**NRIVALLED
**S**ERVICE ALREADY
**I**NSTALLED IN
**O**NLY 2 YEARS IN NEARLY 40,000
**N**IGERIAN WESTERN REGION HOMES

## MO GBADUN SIGA PIRATE




# PIRATE

## ON NI SIGA TO DARA


Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 63 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos. Phone 23390